# ORI OKE ATI IṢẸ IYANU

*Olu Ile Iṣẹ Iranṣẹ, Ipinlẹ Eko, Nigeria.*

**ETO IPADE AGBARA GBỌDỌ PARỌ ỌWỌ**

## ÀBÒ ATOKÉWA

### OṢU KẸRIN, ỌDUN 2020

**Bibeli Kika: Orin Dafidi 91**

**Ijẹwọ: Orin Dafidi 46**

**ORIN IYIN ATI IJỌSIN TI O LAGBARA**

1. Ọlọrun dide ki O si faatu, ohunkohun ti O ko gbin sinu Ijọ Ori oke ina ati iṣẹ iyanu, ni orukọ Jesu.

2. Ọlọrun, jẹ ki ina isọji ba le Ijọ Ori Oke Ina ati Iṣẹ Iyanu, ni orukọ Jesu.

3. Ọlọrun, jẹ ki agbara alafia ati itẹsiwaju ṣiji bo orilẹ-ede yi, ni orukọ Jesu.

4. Ọlọrun dide, ki O si fun wa ni awọn adari ti o bẹru Rẹ, ni orukọ Jesu.

**AWỌN GBOLOHUN AGBARA**

Ọmọ Ọlọrun ni mo jẹ, mo gbagbọ ninu Baba, mo gbagbọ ninu Ọmọ, mo si gbagbọ ninu Ẹmi Mimọ. Mo gbagbọ wipe Jesu Kristi wa ninu ara, O si fi ẹmi Rẹ lelẹ, O ta ẹjẹ Rẹ silẹ fun mi lori igi Agbelebu. Mo gbagbọ wipe Jesu ti ṣẹgun satani, O si ti gba mi lọwọ aye buburu yi pẹlu satani. Mo ti gba Jesu Kristi gẹgẹ bi Oluwa ati olugbala mi, mo jẹ ti Jesu Kristi Oluwa. Jesu Kristi ti san idiyele naa fun mi pẹlu Ẹjẹ Rẹ, O si ti da mi nide, satani ati gbogbo ẹmi eṣu rẹ ko lagbara tabi ijọba lori aye mi mọ, ni orukọ Jesu.

Gbogbo agbara laye ati l'ọrun ni a ti fi fun mi nipasẹ Jesu Kristi. Nipa aṣẹ ti mbẹ ninu orukọ Jesu Kristi, mo ni awọn kọkọrọ si ijọba ọrun, ohunkohun ti mo ba tu ni aye, ni a o tu ni ọrun. Bayi, mo tu ara mi silẹ kuro ninu gbogbo tubu eṣu ati ti awọn ọmọ-lẹyin rẹ, ni orukọ Jesu. Ohunkohun ti mo ba si de ni aye, ni a o de ni ọrun. Bayi, mo gbe de, mo si fi opin si gbogbo oniruuru iṣẹ eṣu ti wọn gbekalẹ lodi si mi, ni orukọ Jesu.

Ọlọrun ti ro mi lagbara, O si ti sọ mi di elewu ati ẹrujẹjẹ si gbogbo awọn ọta mi. Oluwa ti fi ibẹru ati ipaya mi s'ara gbogbo awọn ọta mi, ti o fi jẹ wipe iroyin nipa mi yoo mu wọn bẹru, wariri, wọn a si wa ninu idamu ọkan nitori mi. Ọmọ ogun Kristi ni mo jẹ, mo ngbe gbogbo ihamọra Ọlọrun wọ. Ihamọra Ọlọrun nfun mi lagbara lodi si awọn ijoye, lodi si awọn agbara, lodi si awọn alaṣẹ ibi okunkun aye yi, lodi si iwa-ika t'ẹmi pẹlu gbogbo agbara okunkun. Ile agbara Ọlọrun ni mo jẹ, agbara Ọlọrun ngbe ninu mi, O si nfarahan l'ode. Ogo Ọlọrun jẹ abo yi mi ka, ni orukọ Jesu.

Ni orukọ Jesu Kristi, gbogbo ẹmi eṣu, ati satani paapa ntẹriba fun mi nipasẹ orukọ Jesu. Mo ti gbogbo awọn ọta mi lulẹ, wọn ko si le pa mi lara. Mo ran iparun nla jade lati tuka, lati parun ati lati fọ si wẹwẹ, gbogbo ọta lodi si mi, ni orukọ Jesu. Ko si ete, ọgbọn tabi igbimọ eniyan ika lodi si mi ti yoo duro, gbogbo ahọn ti o ba si dide lodi si mi ni idajọ, mo da wọn lẹbi. Jesu Kristi ti mọ odi yi mi ka, odi abo nla yi mi ka, odi alagbara ti gbogbo awọn ẹmi eṣu ni ọrun-apaadi ati satani funrarẹ ko le rekọja lati wa ba mi, ni orukọ Jesu.

Mo gbagbọ, mo si gba ẹjẹ Jesu Kristi ti a ta silẹ fun mi lori igi Agbelebu, a ti ra mi pada nipa ẹjẹ Jesu. Bayi, mo gbe ẹjẹ Jesu Kristi, mo si lo o gẹgẹ bi odi ti ẹjẹ Jesu layika mi. Mo gba ẹjẹ Jesu Kristi s'or mi ati s'ori ile ti mo ngbe, nigbati ọta ba ri ẹjẹ naa, wọn yo rekọja, awọn apanirun ko ni le wọle nitori ẹjẹ Jesu Kristi. Bi awọn ọta mi ba wa mi, wọn ko ni ri mi, nitori ti aye mi pamọ sinu ẹjẹ Jesu Kristi. Ẹjẹ Jesu Kristi jẹ abo ati ibi isadi fun mi kuro lọwọ gbogbo awọn ọta mi pẹlu satani, ni orukọ Jesu.